# JESU, OLUFUN-NI NI IYÈ

**Johannu 5:1-47; Luku 7:11-16**

**ẸKỌ 41 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Niwọn igba ti mo wà li aiye, emi ni imọlẹ aiye" (Johannu 9:5).**

## Oluwosan lati Ọrun

Jesu kò gbé ni Jerusalẹmu, ṣugbọn O maa n lọ si Tẹmpili nibẹ ni ọjọ àjọ. Ofin fi lélẹ̀ pe gbogbo awọn ọkunrin ni lati lọ si Tẹmpili ni ẹ̀ẹ̀mẹta ni ọdun kan ki wọn si fi ara wọn hàn fun awọn alufaa. Jesu pẹlu si pa Ofin yii mọ kinnikinni.

Ṣugbọn ki i ṣe igba isinmi fun Jesu nigba ti O ba lọ si Jerusalẹmu. Oun maa n fiye silẹ lati wò bi ẹni kan ba wà ti Oun le ṣe iranlọwọ fun. Nigba ti O de ibi Adagun Bẹtẹsda, O ri ọkunrin alailera kan ẹni ti ẹnikẹni kò bikita lati tọju rẹ̀. Lati ọdun mejidinlogoji ni o ti n ṣaisan. Jesu mọ pe o ti pẹ ti ara rẹ ti ṣe aida, aanu alagbe arugbo ti kò ni oluranlọwọ yii ṣe Jesu. Ko si ẹni kan ti oju Olugbala wa fò dá ti ko ni ṣe akiyesi rẹ̀, ko si si ẹni kan ti Oun ki yoo ṣe iranlọwọ fun, nigba ti O ba gbọ igbe ẹni naa ti n ké fun aanu.

Jesu beere boya ọkunrin alailera naa n fẹ ki a mu oun larada. Dajudaju o n fẹ, ṣugbọn kò mọ pe Jesu oniṣẹ-iyanu ni O n ba oun sọrọ, o si ro pe Oluwa n ba oun sọ ti iṣẹ-iyanu ti adagun naa, eyi ti angẹli kan maa n digba rú, ti o si jẹ pe ẹni ti o ba kọkọ wọ inu rẹ̀ ni yoo ri imularada. O ti gbiyanju ni ọpọlọpọ ọdun lati jẹ ẹni kin-in-ni ti yoo wọ inu omi naa lẹyin ti a ba ti ru u, ṣugbọn nitori ailera rẹ oun ko le yara rin, nigba gbogbo bẹẹ ni ẹlomiran maa n ṣaaju rẹ̀. Lẹyin naa oun a maa duro, pẹlu ireti nigba gbogbo pe o pẹ o ya ni oun yoo ni anfaani ni ọjọ kan.

Ṣugbọn ki i ṣe omi ti o le wo kiki eniyan kan ṣoṣo sàn lẹẹkan ni Jesu n sọ nipa rẹ̀. Jesu maa n wo gbogbo awọn ti o ba gbà A gbọ́ san, nigbakiigba, nibikibi. O jẹ ohun iyalẹnu fun wa pe a kò ri ju ẹni kan ṣoṣo ti o ri iwosan leti Adagun Bẹtẹsda lọjọ yii, nitori ọpọlọpọ alailera, afọju, ayarọ, ati amukun, ni o wà nibẹ. Dajudaju Jesu ri ọkan wọn o si le jẹ pe Oun ti ri i pe kò tun si ẹlomiran nibẹ ti yoo gba Oun gbọ́. Jesu kò le ṣiṣẹ nigba ti awọn eniyan kò ba gbà A gbọ́. Ọrọ Iwe Mimọ́ wi bayii nipa Nasarẹti, ilu Oun tikara Rẹ̀: "On kò si ṣe ọ̀pọ iṣẹ agbara nibẹ̀, nitori aigbagbọ́ wọn" (Matteu 13:58).

Iwọ yoo ro pe tayọ-tayọ ni ẹnikẹni yoo fi gba Jesu gbọ́ fun iwosan ara rẹ, ṣugbọn ẹ̀ṣẹ ti o wa ninu ọkan rẹ ti oun kò si fẹ kọ silẹ ni o n fa aigbagbọ́. A o kọ́ diẹ ninu ẹkọ yii nipa ohun ti o jẹ lati gba Jesu gbọ́.

Ọkunrin ti o wà ni eti Adagun Bẹtẹsda ni ọkàn otitọ, si wò o bi ayọ rẹ yoo ti pọ̀ to nigba ti Jesu wi fun un pe Oun yoo mu un larada! Ronu ọpọlọpọ ọdun wọnni ti ko ti ṣe e ṣe fun un lati ṣiṣẹ ounjẹ oojọ́ rẹ̀, ti o si ni lati gbẹkẹle ohunkohun ti awọn eniyan ba fun un. Nisisiyii o le nikan da wà fun ara rẹ lẹẹkan si i, ki o si lọ si ibikibi ti ọkàn rẹ ba n fẹ. Jesu maa n fi pupọ lọ eniyan A si maa beere diẹ, ṣugbọn ọpọlọpọ eniyan ni wọn n kọ̀ sibẹ lati fi diẹ ni silẹ. I ba ti daa to bi wọn ba le mọ bi ibukun ti wọn n sọnu ni aye yii ti pọ to nipa kikọ̀ Olugbala silẹ, ki a ma ṣẹṣẹ wa sọ ti idalẹbi ayeraye ti n duro de wọn nigba ti wọn ba fi aye silẹ!

## Awọn Alariwisi

Dipo ti awọn eniyan i ba fi mọ riri ohun ti Jesu ṣe fun awọn ẹlomiran, ọ̀ràn ariwisi ni wọn maa n gbiyanju lati wa. Jesu ti sọ fun ọkunrin naa pe ki o gbe akete rẹ ki o maa lọ. Inu ọkunrin yii dùn pupọ pe oun tun le rin to bẹẹ ti o fi le ru ẹru ti o si fi itara gbọ́ràn si aṣẹ Jesu. Ṣugbọn awọn Farisi wọnni wà nibẹ, awọn ti kò laanu. Dipo ti wọn i ba fi maa yọ̀ pe ọkunrin alaisan yii tun le rin ti kò si tun ni maa ṣagbe mọ́, wọn bẹrẹ si i ba a wi pe o n ru akete rẹ̀ ni ọjọ Isinmi. Ọkunrin yii ko i ti mọ ẹni ti o mu oun larada sibẹ; kò mọ pe Jesu pẹlu ni Oluwa ọjọ Isinmi. Jesu ti kuro ni agbegbe adagun naa lẹyin iṣẹ-iyanu ti aanu ti O ṣe lai duro gba ọpẹ.

## Ifi Imoore Hàn

Ọkunrin alaisan yii jẹri si igbagbọ́ ti o ni ninu Jesu, nitori igba miiran ti a tun gbọ nipa rẹ, ninu Tẹmpili ni o wà, o si ni lati jẹ pe o lọ sibẹ lati lọ dupẹ lọwọ Ọlọrun fun idasilẹ rẹ. Akọsilẹ wà ninu Ofin Lefi pe nigba ti awọn eniyan ba ri iwosan ninu arun kan wọn ni lati tọ awọn alufaa lọ ki awọn alufaa le yà wọ́n si mimọ́. Eyi ni idi rẹ ti Jesu fi sọ fun awọn adẹtẹ mẹwaa ti O ti mu lara da lati fi ara hàn fun awọn alufaa (Luku 17:14).

Nigba ti Jesu ri ọkunrin yii ti O ti mu lara da ni Tẹmpili, O ni, "Wo o, a mu ọ larada: máṣe dẹṣẹ mọ́, ki ohun ti o buru jù yi lọ ki o má bà ba ọ." Nigba naa ni ọkunrin ti a mu lara da yii mọ̀ pe Jesu ni, nitori ko si ẹlomiran ti o le fi ẹ̀ṣẹ ji ni.

Awọn Ju n binu nitori Jesu mu ọkunrin abirun naa lara da ni Ọjọ Isinmi, ṣugbọn Jesu kò lọ́ra lati sọ fun wọn gbangba pe ẹlẹṣẹ ni wọn i ṣe. Wọn n jalankato pe awọn n tọ Ọlọrun lẹyin timọtimọ, ṣugbọn Jesu sọ fun wọn pe: "Ẹ kò si ni ọ̀rọ rẹ̀ lati ma gbé inu nyin: nitori ẹniti o rán, on li ẹnyin kò gbagbọ́." A ri i pe lati jẹ Onigbagbọ́ ju pe ki a kan gba Ọlọrun gbọ́ ṣá. A ni lati ni Ọrọ Ọlọrun (eyi ni Jesu) ki O maa gbé inu wa. Awọn Ju ti Jesu n ba sọrọ ni akoko yii rò pe awọn ti mura tan fun Ọrun -- wọn tilẹ rò pe awọn n gbé igbesi-aye wọn gẹgẹ bi Ọrọ Iwe Mimọ́.

Ṣugbọn Jesu wi fun wọn pe ki wọn tubọ yẹ ara wọn wò diẹ si i -- wọn ti sọ ohun kan nù. "Ẹnyin nwá inu iwe mimọ́ nitori ẹnyin rò pe ninu wọn li ẹnyin ni iye ti kò nipẹkun."

**Gbagbọ́ ki o si Yè**

A ti n ka akọsilẹ Mose ninu eyi ti Ọlọrun ṣe ileri Messia fun Abrahamu, Isaaki ati Jakọbu. Ninu Deuteronomi 18:15, Mose kọwe pe: "OLUWA Ọlọrun rẹ yio gbé wolĩ kan dide fun ọ lãrin rẹ, ninu awọn arakunrin rẹ, bi emi, on ni ki ẹnyin ki o fetisi." Mose sọrọ nipa Jesu, bi awọn eniyan naa ba si ti gba akọsilẹ Mose gbọ́, gẹgẹ bi wọn ti n wi, wọn i ba ti gba Jesu gbọ́. Wò o bi o ti ṣe ohun pataki to pe ki Ọrọ Ọlọrun maa gbé inu wa, ki a ma kan maa rò lasan pe a ni iye ainipẹkun: "Ẹniti kò ba si gbà Ọmọ gbọ, ki yio ri ìye; ṣugbọn ibinu Ọlọrun mbẹ lori rẹ̀ (Johannu 3:36).

Jesu wi pe, "Ẹnikẹni ti o ba gbọ́ ọ̀rọ mi, ti o ba si gbà ẹniti o rán mi gbọ́, o **ni** iye ti kò nipẹkun." O ti ni iye naa nihin, ati lẹyin ti o ba kú. Eyi yii n fi hàn fun wa pe ohun ti Jesu n pe ni "iye" ju mímí, jijẹ, sisùn, ati irin kaakiri lọ. Bi a kò bá ni Jesu ninu wa a ti kú. "Ṣugbọn ẹniti o ba fi ara rẹ̀ fun aiye jijẹ, o kú nigbati o wà lãye" (1 Timoteu 5:6). Ṣugbọn awọn ti o gbọ́ ohùn Jesu ti wọn si gbọran si ohùn Rẹ̀ ni a sọ di alaaye nipa ti ẹmi.

Jesu nikan ṣoṣo ni O le fun ni ni iye ainipẹkun yii. O wi fun awọn Ju pe wọn kò le ni iye ainipẹkun nitori wọn kò tọ Oun wá lati gbà á (iye ainipẹkun). Jesu n pe gbogbo eniyan lati wá gba iye: "Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o fi Ọmọ bibi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni iye ainipẹkun" (Johannu 3:16). "Emi li ọ̀na, ati otitọ, ati iye: kò si ẹnikẹni ti o le wá sọdọ Baba, bikoṣe nipasẹ mi" (Johannu 14:6).

**Agbara Ajinde**

Jesu ni agbara lori iyè ati ikú. "Nitorina ni Baba mi ṣe fẹran mi, nitoriti mo fi ẹmí mi lelẹ, ki emi ki o le tún gbà a … Mo li agbara lati fi i lelẹ, mo si li agbara lati tun gbà a" (Johannu 10:17, 18). Nihin yii O n sọrọ nipa ara ti O gbé wọ̀ ni ayé yii bi o tilẹ jẹ pe kò ka ara wa ti ayé yii si nnkan ti o ṣe pataki lọ titi, O mọ̀ pe o jẹ ohun pataki pupọ fun wa, Oun a si maa ṣe iranlọwọ fun awọn ọmọ Rẹ̀. A ti ri ninu ẹ̀kọ́ yii bi Jesu ti sọ igbesi-ayé ọkunrin abirun yii ti o wà leti Adagun Bẹtẹsda di ọtun. Bakan naa ni O mu inu opo Naini dùn nigba ti O ji ọmọ rẹ ti o ti kú dide. O tun ji Lasaru dide nitori Maria ati Marta n fẹ iranlọwọ Rẹ̀, ati ki awọn eniyan ba le ri i pe O ni agbara lati ṣe e. Jesu maa n gbọ́ adura wa, A si maa ṣe ọpọlọpọ ohun nla fun ire wa – ati fun ogo Rẹ̀.

Nigba ti Jesu ba tun pada bọ̀ gbogbo awọn Onigbagbọ́ aṣẹgun ni yoo lọ soke nigba Ipalarada. Awọn ti o ti kú yoo pada di ààye nigba ti Jesu ba pè wọn. Jesu wi pe, "Nitoriti emi wà lãye, ẹnyin ó wà lãye pẹlu" (Johannu 14:19). "Awọn okú ninu Kristi ni yio si kọ́ jinde: nigbana li a ó si gbà awa ti o wà lãye ti o si kù lẹhin soke pẹlu wọn sinu awọsanma lati pade Oluwa li oju ọrun: bẽli awa ó si ma wà titi lai lọdọ Oluwa" (1 Tẹsalonika 4:16, 17). Daniẹli paapaa sọ nipa igba yii ninu Majẹmu Laelae: "Ati ọ̀pọlọpọ ninu awọn ti o sùn ninu erupẹ ilẹ ni yio ji, awọn miran si iye ainipẹkun, ati awọn miran si itiju ati ẹ̀gan ainipẹkun" (Daniẹli 12:2).

Bibeli ni Ọrọ Ọlọrun, "Ọ̀rọ na si di ara, on si mba wa gbé" – eyi i ni ni Jesu. "Nitoripe gẹgẹ bi baba ti ni iye ninu ara rẹ̀; gẹgẹ bẽli o si fifun Ọmọ lati ni iye ninu ara rẹ̀." Nitori naa bi iye ba wà ninu Jesu, ti o jẹ pe Ọrọ naa ni Jesu, nigba naa iye wà ninu Ọrọ naa. Jesu ni, "Ọ̀rọ wọnni ti mo sọ fun nyin, ẹmi ni, ìye si ni" (Johannu 6:63). A ni lati ṣọra ki a si maa gbọran si ohun ti Bibeli wi nitori ki i ṣe okú iwe, ṣugbọn Ọrọ Ọlọrun ti iye wà ninu rẹ ni, eyi ti Ẹmi Mimọ́ mi si awọn eniyan mimọ́ lati kọ.

A tọ́ ọmọdebinrin kekere kan dagba ninu ẹsin kan ti ko gbà a laye lati ka Bibeli rara. Ni ọjọ kan o n ka iwe akewi ti o ni ẹsẹ-ọrọ diẹ lati inu Bibeli ninu. O ri iyatọ lẹsẹkẹsẹ. O mọ iye ti o wà ninu ọrọ ti o ti inu Iwe Mimọ́ jade. O bẹrẹ si poungbẹ lati ni Bibeli kan fun ara rẹ, ni ọjọ kan oṣiṣẹ Onigbagbọ́ kan fun un ni ọ̀kan. Ebi Ounjẹ Iye n pa a to bẹẹ gẹẹ ti o fi bẹ̀rẹ̀ si i ka a lati ibẹrẹ, o si n ka a lati ori kan si ẹkeji. O fẹ lati mọ ifẹ Ọlọrun. Nigba ti o de Ofin Mẹwaa, ti o si kà, "Iwọ kò gbọdọ li ọlọrun miran pẹlu mi" ati pe "Iwọ kò gbọdọ yá ere fun ara rẹ. … iwọ kò gbọdọ tẹ̀ ori ara rẹ ba fun wọn," o kọ ẹsin rẹ̀ silẹ o si ke pe Ọlọrun fun aanu ati idariji fun awọn ẹ̀ṣẹ rẹ. Jesu gbà a là, O si fun un ni iye ainipẹkun.

## AWỌN IBEERE

1 Njẹ ọkunrin abirun naa mọ ẹni ti o mu oun lara dá?

2 Ki ni itumọ "sisọ ni di ãye?"

3 Ki ni Jesu sọ nipa wiwá ọlá fun ara wa?

4 Apẹẹrẹ meloo ni o le ri ninu Majẹmu Titun nipa jiji ti Kristi ji oku dide?

5 Njẹ Jesu kọ̀ ni ọjọ kan ri lati wo ni sàn tabi lati ṣe iranlọwọ fun awọn ti wọn tọ Ọ wá?